# IWA ONIGBAGBỌ́ - NINU ILE ATI LAAARIN IJỌ

**Efesu 6:1-4**

**ẸKỌ 356 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: “Njẹ nisisiyi, ẹ fetisi temi, ẹnyin ọmọ: nitoripe ibukun ni fun awọn ti o tẹle ọ̀na mi” (Owe 8:32).**

## I Iṣẹ Awọn Ọmọ ati Awọn Obi

1 O yẹ fun awọn ọmọ lati gbọ́ ti awọn obi wọn ninu Oluwa, Efesu 6:1; Owe 23:22; Kolosse 3:20

2 Bi wọn ba bu ọla fun baba ati iya wọn, ileri wà pe wọn yoo gbadun ọjọ ayé wọn pẹ́ titi, Efesu 6:2, 3; Ẹksodu 20:12; Deuteronomi 5:16; Jeremiah 35:18, 19; Matteu 15;4

3 Awọn obi ni lati fi iwa pẹlẹ bá awọn ọmọ wọn lò, ki wọn si tọ́ wọn ninu ibẹru Ọlọrun, Efesu 6:4; Deuteronomi 4:9; 11:19; Orin Dafidi 78:4-8; Owe 19:18; 22:6; 29:17

## ALAYE

### Ilé

Alaye kikun wa ninu Bibeli nipa iṣẹ awọn obi si awọn ọmọ ati iṣẹ awọn ọmọ si awọn obi. Ilé jẹ́ igbekalẹ Ọlọrun. Ọlọrun ṣe ilana rẹ̀ lati jẹ́ ọ̀kan ṣoṣo. Ni atetekọṣe Ọlọrun ri i pe kò yẹ ki ọkunrin ki o nikan wà, o si fun un ni oluranlọwọ kan. A sọ fun ni pe ọmọ ni iní Oluwa.

Ẹrù nlá nlà ni o wà lori awọn obi. “Bi ilé ti ri, bẹẹ gẹgẹ ni orilẹ-ède ri.” Ilé ni agbara orilẹ-ède. Owe lailai miiran tun sọ pe: “Ọwọ́ ti o gbé ọmọ ikoko (jojolo) lo n ṣakoso gbogbo agbaye.” Bi ilé wa ba fọ́ ti o si pín si wẹwẹ, lai pẹ titi orilẹ-ède wa yoo fọ́ pẹlu. Bi awọn ilé wa ba jẹ́ ilé Onigbagbọ́ tootọ, a o ni orilẹ-ède ti ọta ki yoo le bori.

Nigba ti Oluwa tipasẹ Mose bá awọn Ọmọ Israẹli dá majẹmu, gbogbo wọn lo ni lati fi ara hàn niwaju Rẹ̀ -- awọn olori wọn, awọn alagba wọn, awọn alabojuto wọn ati awọn alejo (Deuteronomi 29:9-12). Gbogbo ẹbi ni o gbọdọ wá lati wá sin Oluwa. Nigba ti Joṣua wọ ilẹ Kenaani, o tẹ́ pẹpẹ kan sori oke Ebali o si ṣe ẹbọ sisun ati ẹbọ alaafia. O kọ awọn Ofin Mose sara okuta ni oju gbogbo awọn Ọmọ Israẹli. Bẹẹ ni o si tun ka gbogbo ọ̀rọ ofin naa si eti igbọ́ gbogbo apejọ Israẹli, pẹlu awọn obinrin, awọn ọmọ wẹwẹ wọn ati awọn alejo ti o wa laaarin wọn (Joṣua 8:30-35). Ọlọrun ṣe igbekalẹ ijọsin fun gbogbo ẹbi.

Ni akoko ti Kristi, awọn obi fẹ lati gbé ọmọ wọn tọ Jesu wá ki o le sure fun wọn. Awọn ọmọ-ẹyin dá wọn lẹkun wọn si n fẹ lé wọn sẹyin, ṣugbọn Jesu wi pe: “Ẹ jẹ ki awọn ọmọ kekere ki o wá sọdọ mi, ẹ má si ṣe da wọn lẹkun: nitoriti irú wọn ni ijọba Ọlọrun” (Ka Marku 10:13-16). A ri bi ẹkọ Jesu ti n tẹle ilana Ofin ni mimú ọmọde wá jọsin ni ilé Ọlọrun. Wo bi o ti yẹ ki awọn ọmọde ṣe jẹjẹ ki wọn si ṣe ohun gbogbo tọwọtọwọ ni ilé-isin! A gbọdọ jẹ ki wọn mọ̀ nipa apẹẹrẹ ati igbani-niyanju awọn obi wọn pe iwaju Ọlọrun ni wọn wà nitootọ.

### Isin Agbo-ilé

Igbekalẹ̀ miiran ti Oluwa bukún ni isin agbo-ilé. Ni ilé awọn Onigbagbọ atijọ́, awọn obi a maa kó gbogbo ẹbi jọ ni ẹẹkan tabi ẹẹmeji nigba miiran loojọ lati ka Ọrọ Ọlọrun ati lati gbadura. Wo irú ibukun nla ti yoo wá si irú ilé bẹẹ! O ṣoro fun ni lati gbagbọ́ pe ọ̀pọ awọn alaigbagbọ́ ni a tọ́ ninu ilé ti ifẹ Ọlọrun wà nibi ti awọn obi jẹ olooototọ lati kọ́ awọn ọmọ wọn ni Ọrọ Ọlọrun.

Labẹ Ofin, gbogbo ile ni lati gbọ́ Ọrọ Ọlọrun ki wọn si gbọran si i. “Gbọ́, Israẹli: OLUWA Ọlọrun wa, OLUWA kan ni. Ki iwọ ki o si fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo agbara rẹ fẹ́ OLUWA Ọlọrun rẹ. Ati ọrọ wọnyi ti mo palaṣẹ fun ọ li oni, ki o ma wà li àiya rẹ: Ki iwọ ki o si ma fi wọn kọ́ awọn ọmọ rẹ gidigidi, ki iwọ ki o si ma fi wọn ṣe ọ̀rọ isọ nigbati iwọ ba joko ni ile rẹ, ati nigbati iwọ ba nrin li ọ̀na, ati nigbati iwọ ba dubulẹ, ati nigbati iwọ ba dide” (Deuteronomi 6:4-7).

Iṣẹ awọn obi ni nigba gbogbo lati fi Ọrọ Ọlọrun kọ awọn ọmọ wọn ni ile. Ọpọlọpọ ni o fi iṣẹ yii silẹ fun olukọ ile-ẹkọ Ọjọ Isinmi tabi fun oniwaasu lati ṣe ni Ọjọ Isinmi. Oluwa sọ nipa ti Abrahamu pe: “nitoriti mo mọ̀ ọ pe, on o fi aṣẹ fun awọn ọmọ rẹ̀ ati fun awọn ara ile rẹ̀ lẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o ma pa ọ̀na OLUWA mọ́ lati ṣe ododo ati idajọ” (Gẹnẹsisi 18:19). A le ri i nihin irú igbẹkẹle ti OLUWA ni ninu Abrahamu. Njẹ O ha ni irú igbẹkẹle bẹẹ ninu wa lonii?

Ọ̀kan ninu awọn ibi igba isisiyii ni pe awọn ọmọ ni o n ṣe akoso awọn obi wọn, ki i ṣe awọn obi ni o n ṣe akoso awọn ọmọ wọn. Wo bi awọn ọdaran ọmọ ti pọ̀ tó nitori awọn irú iwa bayii! A mọ iru idajọ ti

o wa sori Eli, alufaa, nigba ti awọn ọmọ rẹ̀ sọ ara wọn di ẹlẹgbin ti oun kò si dá wọn lẹkun. Bi Oluwa ba fi awọn ọmọ si itọju wa, a gbọdọ fi akoko silẹ lati boju to wọn. Wọn ni ẹmi ti ki i kú, nitori bẹẹ a kò gbọdọ jẹ ki wọn dagba bi ọmọ ti kò ni ilé, ti o dagba si oju títì, lai fi Ọrọ Ọlọrun kọ́ wọn.

### Iṣẹ Awọn Obi si Awọn ọmọ Wọn

"Ẹnyin baba, ẹ máṣe mu awọn ọmọ nyin binu." Ki a bá ọmọde wi, ki a si nà wọn jẹ́ ẹkọ ti a kọ́ ni yekeyeke ninu Bibeli. Ẹṣẹ abinibi ti a bi mọ́ awọn ọmọ yoo ti wọ̀n lọ sinu ọ̀pọlọpọ iwa buburu ati iwa ẹ̀ṣẹ bi kò ṣe pe awọn ọbi ba gbà á ni iṣẹ lati maa ṣọ́ wọn ati lati dá wọn lẹkun. O gba ọ̀pọlọpọ ọgbọ́n ati ifẹ́ Ọlọrun lati lè tọ́ ọmọde si ọna ti o tọ́. Awọn obi miiran a maa bá awọn ọmọ wọn binu wọn a si maa gba wọn sibi gba wọn sọhun: eyi fẹrẹ buru ju ki a má tilẹ jẹ wọn niya rara. Bi awọn obi yoo ba fi inu tán awọn ọmọ wọn ki wọn si maa fi ifẹ ati inurere ṣe alaye iyatọ ti o wà laaarin rere ati buburu, eyi yoo jẹ ki o yé ọmọ naa gbangba idi rẹ̀ ti a fi n jẹ oun niyà. Awọn obi miiran a maa bá awọn ọmọ wọn gbadura pọ̀ ki wọn to jẹ wọn niya, eyi yii dara paapaa nigba ti ọmọ naa bá ti dagba tó lati ni oye to bẹẹ. Ọdọmọkunrin ọmọ ọdún mejila kan wa ni ilé kan ti o korira obinrin kan ti n gbé ibẹ̀, a si maa sọ ọ̀rọ buburu si obinrin naa. Iya ọmọ yii a si pe e wọ inu yara a si sọ fun un pe oun ki yoo gba a laye lati maa sọrọ bẹẹ. Lẹyin eyi awọn mejeeji a si jọ gbadura. Ni ọjọ kan iya rẹ̀ tun pe e wọ inu yara, ọmọ yii si sọ pẹlu iyanu pe, "Iya, emi kò ti i sọ ohunkohun lati igba ti a ti jọ gbadura."

### Ile-Ẹkọ Gbogbo-gboo

Awọn Ile-ẹkọ ti gbogbo-gboo dabi ẹni ti n rò pe awọn ti jogun awọn ọmọ wa, wọn si n fẹ ni aṣẹ kikún lati tọ́ wọn si ọ̀nakọna ti o bá tẹ́ wọn lọrun. Wọn ti ṣe ilana ẹkọ silẹ eyi ti yoo ṣoro fun awọn obi ti o ba jẹ́ Onigbagbọ́ lati fi ara mọ́ patapata. Ijó jijó, ọ̀kan ninu awọn ibi ti o ga ju lọ ni ode oni ni a n kọ́ awọn ọmọ ni ọ̀pọlọpọ ile-ẹkọ. Aṣọ ti wọn n wọ̀ ṣire idaraya paapaa lodi si ẹkọ ti o yẹ fun awọn ọmọ Onigbagbọ́. Awọn iwe ti ó wà ni ile-ikawe wọn gbogbo ki i ṣe iru eyi ti o yẹ ki ọmọ Onigbagbọ́ maa kà. Awọn obi miiran maa n ṣe ayẹwo awọn iwe ti awọn ọmọ wọn n gbà lati ile-ikawe wá kà ni ile; bi wọn kò ba yẹ ni kika fun awọn ọmọ, wọn a dá wọn pada. O yẹ ki gbogbo awọn obi maa ṣe eyi. Ẹkọ ti a ba fi kọ́ awọn ọmọ wa ni wọn yoo dagba sinu rẹ̀.

### Igbagbọ́ Rọrun

Ọkan ọmọde rọ̀ pupọ. Bi awọn obi kò ba ti i tan ọmọde jẹ nigba kan ri, yoo gbẹkẹle wọn patapata. A le kọ́ ọmọde nipa Jesu ni igbakigba ti ọmọ naa ba ti le pe Orukọ Jesu. Otitọ igbagbọ́ wọn yoo maa doju ti awọn obi wọn nigba pupọ. Ni igba miiran awọn obi ti ara wọn ṣe alaidá maa n ri iwosàn nipa adura ọmọde. Ọkan ọmọde ki i pẹ́ gbọgbẹ́ nitori naa o yẹ ki awọn obi maa ṣọra bi wọn ṣe n sọrọ ati bi wọn ṣe n huwa niwaju wọn. Wo bi o ti jẹ́ ojuṣe nlá nlà tó lati tọ́ ọmọde ni ọ̀na ti yoo tọ̀!

### Aigbọran si Obi

Ninu Iwe ti Paulu kọ si Timoteu o sọ wi pe ni ikẹyin ọjọ awọn ọmọ yoo jẹ́ aṣaigbọran si obi. Ninu ile meloo lonii ni o ti le ri awọn ọmọ ti o gbọran si obi? Ni ọdun diẹ sẹyin, eṣu ṣe eto ọgbọ́n ẹ̀wẹ̀ ti o buru jai ju eyi ti a le fi ọkàn rò lọ lati ba ayé awọn ọmọ wa jẹ́. O yọ́ kẹlẹ wọ inu ọkàn awọn olukọni wa lati maa sọ pe awọn ọmọde gbọdọ ni ominira lati huwa, lati ronu ati lati ṣe bi wọn ba sa ti fẹ́ lai si idiwọ tabi idalẹkun ẹnikẹni, bi kò ṣe pe ki a gbà wọn laye lati dagba gẹgẹ bi wọn ti n fẹ́. Eso irugbin ẹkọ yii ni orilẹ-ède n ká lonii. Kò si igba ti iwa ailofin gbilẹ ri bi ti akoko yii. Pupọ ninu awọǹ ọdaran ode-oni jẹ́ awọn ọmọ ti ọjọ ori wọn kò tó ogún ọdún.

A ko le ṣá ỌrọỌlọrun tì ki a si ni ireti pe ki awọn ọmọ wa jẹ́ apẹẹrẹ rere. Bibeli sọ pe, "Li aiya ọmọde ni wère di si; ṣugbọn paṣan itọni ni yio le e jina kuro lọdọ rẹ̀" (Owe 22:15). Ohun ti ẹkọ wa palaṣẹ ni pe "Ẹnyin ọmọ, ẹ mã gbọ ti awọn obi nyin ninu OLUWA: nitoripe eyi li o tọ́." Wo bi yoo ti dun mọ ni to lati lọ si ile kan nibi ti a gbé n kọ́ awọn ọmọ lati gbọran!

"Bọ̀wọ fun baba ati iya rẹ: (eyi ti iṣe ofin ikini pẹlu ileri)." Ileri naa ni, "Ki o le dara fun ọ, ati ki iwọ ki o le wà pẹ li aiye." Obi meloo ni o ti joko ti wọn ti bá awọn ọmọ wọn jiroro ti wọn si ti sọ fun wọn nipa ofin yii ati ileri iyanu ti OLUWA ti ṣe. O rọrun fun awọn ọmọde lati gbọran si OLUWA bi a ba ti kọ́ wọn lati maa gbọran si awọn obi ninu ile. A ni awọn apẹẹrẹ rere diẹ ninu Bibeli nipa awọn ọmọde ti igbesi-ayé wọn jẹ́ ẹkọ: Isaaki, Josẹfu, Samuẹli, Timoteu ati awọn miiran bẹẹ bẹẹ.

### Awọn ọmọde gẹgẹ bi Apẹẹrẹ

A gba awọn ọmọde niyanju pe ki wọn ranti Ẹlẹda wọn ni igba èwe wọn. "Iṣe ọmọde pãpa li a fi imọ ọ, bi iwa rẹ̀ ṣe rere ati titọ" (Owe 20:11).

Awọn ọmọde ni ipa ti wọn ninu Ihinrere, a si ni awọn apẹẹrẹ diẹ ti o yanilẹnu ti Oluwa ti lò lati sọ nipa Ọlọrun ati lati fi ayọ ati inudidun fun ẹlomiran. A ranti ẹrubinrin kekere kan ti o sọ fun olori-ogun Siria nì nipa bi o ti ṣe le ri iwosan gba ni ilẹ Israẹli. O wá, ki isi ṣe pe o ri iwosan gbà nikan, ṣugbọn o ri igbala fun ọkàn rẹ̀ pẹlu.

Lẹyin naa, a tún ranti Samuẹli ọmọkunrin kekere ti iya rẹ̀ ti yà sọtọ lati fi gbogbo ayé rẹ̀ fun iṣẹ-isin ni ile Ọlọrun. A maa ṣe iranṣẹ fun alufaa ninu Tẹmpili, o si dagba, o di wolii Ọlọrun tootọ, alagbayọri adura nla, ati ẹni ti n jere ọkàn.

A tún ranti ọmọkunrin kekere ni pẹlu, ẹni ti o yọọda ounjẹ rẹ̀ fun Jesu ki o le fi bọ́ ọ̀pọlọpọ eniyan. Gbogbo apẹẹrẹ wọnyii yẹ ki o fun awọn ọmọde ni iṣiri lati maa gbọran si awọn obi wọn ati si Oluwa.

Ronu nipa awọn ọmọ kekere laaarin ogunlọgọ eniyan ti wọn n ya imọ-ọpẹ sọna fun Jesu nigba ti o gun kẹtẹkẹtẹ wọ Jerusalẹmu. Gbọ́ ohun awọn ewe ti n kigbe: “Hosanna fun Ọmọ Dafidi: Olubukun li ẹniti o mbọ̀ wá li orukọ Oluwa” (Matteu 21:9).

Lonii a n reti ki Jesu tun pada wá. Bawo ni awọn ọmọ wọn ni yoo ti yọ̀ pọ̀ tó, ti wọn yoo gbọ́ ohun ipe nitori igbe ayé iwa mimọ́ ti wọn n gbé, wọn yoo si kigbe pe, “Hosanna fun Ọmọ Dafidi: Olubukun li ẹniti o mbọ̀ wá!”

**AWỌN IBEERE**

1 Sọ awọn ẹsẹ Bibeli ti o fi hàn pe awọn ọmọde gbọdọ gbọran si awọn obi wọn lẹnu.

2 Sọ diẹ ninu awọn ayọrisi aigbọran awọn ọmọ si obi.

3 Ka ofin kin-in-ni pẹlu ileri.

4 Sọ ọ ni ọ̀rọ ti rẹ awọn aṣẹ ti Mose fi fun awọn obi, ibi ti o yẹ ati igba ti o yẹ lati maa fi ọrọỌlọrun kọ́ ni.

5 Ka awọn ọ̀rọ ti Jesu sọ lati ori nipa wiwá awọn ọmọde si ọdọ Rẹ̀.

6 Darukọ awọn eniyan diẹ lati inu Bibeli ti wọn ṣe akoso ile wọn daradara.